# OMINIRA WA NINU KRISTI

**Galatia 4:1-31; 5:1-15**

**ẸKỌ 399 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Nitorina ẹ duro ṣinṣin ninu ominira na eyi ti Kristi fi sọ wa di ominira, ki ẹ má si ṣe tún fi ọrùn bọ àjaga ẹrú mọ́" (Galatia 5:1).**

**I Arole Kristi**

1 Arole wà labẹ idè titi yoo fi dagba tó, Galatia 4:1-3; Luku 2:51.

2 A rán Kristi lati rà wá pada kuro labẹ idè, Galatia 4:4-7; Johannu 8:36, Romu 10:3.

3 Lẹyin ti a ti di ominira, ki ni ṣe ti a tun n pada sinu isinru? Galatia 4:8-10; Romu 6:2; 2 Peteru 2:19-22.

4 Wọ́n fi tayọ̀tayọ̀ gba Ihinrere ti Paulu waasu rẹ̀, Galatia 4: 16-21; 1:6, 7.

**II Majẹmu Meji**

1 A fi awọn ọmọ Abrahamu mejeeji ṣe apejuwe, Galatia 4: 22-24; Gẹnẹsisi 17:15-21; 21:9-13.

2 Iṣmaẹli jẹ́ apẹẹrẹ Ju nipa ti ara, Galatia 4:25, 29

3 Isaaki jẹ́ apẹẹrẹ Ju nipa ti ẹmi, Galatia 4:26-28; Romu 2:28, 29

4 Ju nipa ti ẹmi wà ni ominira, Galatia 4:30, 31; Romu 6:22; 8:15, 16.

**III Ipè Si Ominira**

1 Ẹ duro ṣinṣin ninu ominira ninu eyi ti Kristi fi sọ wa di ominira, Galatia 5:1-6.

2 Awọn ẹlẹkọ eke n di ominira lọwọ, Galatia 5:7-12.

3 Ifẹ kó Ofin já, Galatia 5:13-15; Romu 13:8-10; 1 Kọrinti 13:4-7.

## ALAYE

### Àrólé

Nigba pupọ bi a ba fi ohun ini silẹ fun ọmọdekurin, a ki i gba a laye fi ọwọ kan an titi yoo fi dagba tó. Nigba ti o wà ni ọmọde yoo maa lọ si ile ẹkọ gẹgẹ bi awọn ọmọ miiran ti wọn le jẹ́ talaka. Gẹgẹ bi ọmọde kò si iyatọ rara laaarin wọn. Bẹẹ gẹgẹ ni a ri i ti Apọsteli naa n fi otitọ ọmọ yii yé wa pé nigba ti Kristi wá, awa wà gẹgẹ bi ewe ti o ṣẹṣẹ n goke agba ti oye si bẹrẹ si i yé nipa ominira ti i ṣe ajogunba wa. Wo iru ominira ti ọmọdekunrin naa bẹrẹ si jẹ igbadun rẹ̀! Oun kò tun ni gbọ́ pe: "Maṣe fi ọwọ́ rẹ kan eyi ni!" "Fi iyẹn silẹ!" "O kò le mú yẹn!" Gbogbo kikalọwọ-kò atijọ ti kuro; ogún naa di ti rẹ̀; oun ti dagba.

### Idè Ofin

Ofin pẹlu ọpọlọpọ ilana rẹ̀ mu awọn eniyan wá sinu idè. Eyi ri bẹẹ nitori pe wọn kò mọ̀ nipa idalare nipa igbagbọ́. Wọn n lọ kaakiri wọn si n gbé ododo ara wọn kalẹ nipa iṣẹ Ofin. "Nitori bi nwọn kò ti mọ ododo Ọlọrun, ti nwọn si nwá ọna lati gbé ododo ara wọn kalẹ, wọn kò tẹriba fun ododo Ọlọrun" (Romu 10:3). Lọjọ oni pẹlu, iru ọna kan naa ni awọn eniyan n gbà nipa ṣiṣai wá sọdọ Kristi fun idariji. Wọn n gbidanwo lati pa Ofin Wura mọ́. Wọn tilẹ n fi ipa sẹ́ ara wọn lati yẹra fun awọn nnkan wọnni ti i ṣe ibi. Gbogbo nnkan wọnyii tubọ n fà wọ́n sinu idè ni. Bi wọn ba jẹ́ tọ Kristi wá ki a si gbà wọn là, iwa-aye wọn gan an yoo yipada wọn yoo si mọ ominira jijẹ́ ọmọ Ọlọrun.

Itumọ eyi ni pe Onigbagbọ ki i hu iwa ẹ̀ṣẹ, nitori pe a ti mú ifẹ ẹ̀ṣẹ jade. Idè Satani ti tú kuro, oun si di ominira lati maa gbé ayé gẹgẹ bi ọkàn rẹ̀ ti n fẹ́. Eyi ni ominira tootọ. Ẹlẹṣẹ wà ninu idè lati maa dẹṣẹ. O le ri pe ọti mimu kó oun lẹru. O si n fẹ́ fi iwa ọti mimu silẹ, ṣugbọn kò le ṣe e. Nigba ti o ba tọ Kristi wá, ẹ̀wọn ẹ̀ṣẹ wọnni yoo já. Nigba ti a ba si da a silẹ bẹẹ tan ẹni naa yoo le gbé igbesi-aye (rere) ti

o ti n fẹ́ lati maa gbé nigba ti o wà labẹ akoso Satani; ṣugbọn ti ko ṣe e ṣe nitori ti o wà labẹ idè. “Nitorina bi Ọmọ ba sọ nyin di omnira, ẹ ó di omnira nitõtọ” (Johannu 8:36).

Njẹ ẹnikẹni ti Kristi ti sọ di ominira gbọdọ tun ni ọkàn lati pada sinu idè bi? Njẹ ẹnikẹni ti ọti-mimu ti kó lẹru ṣugbọn ti a dá nide gbọdọ tun maa gbidanwo lati ṣe rere nipa agbara oun-tikara rẹ̀ lẹyin ti o ti mọ ominira kuro labẹ ifẹ ẹ̀ṣẹ lẹẹkan bi?

**Awọn Wolii Eke**

“Ẹnyin nkiyesi ọjọ, ati oṣù, ati akokò, ati ọdun.” Njẹ a kò ha le sọ eyi nipa awọn ti n kiyesi Ọjọ Isinmi awọn Ju lonii? Wọn yoo tun mu wa pada sabẹ ide Ofin ninu eyi ti Kristi ti sọ wa di ominira. Nitori Kristi li opin ofin si ododo fun olukuluku ẹniti o gbagbọ́” (Romu 10:4).

Nigba ti Paulu kọ́ waasu Ihinrere fun awọn ara Galatia, wọn fi igbona ọkàn gbà á. Wọn gba a (Paulu) bi “angẹli Ọlọrun.” Wọn tilẹ n fẹ yọ oju wọn jade fun un. Ki ni fa iyipada nisisiyii?

Awọn wolii eke ti wọ aarin wọn, wọn si ti yi ọkàn wọn pada kuro ninu otitọ. Awọn ti wọn ni itara fun Ofin Mose n fẹ́ mu awọn ara Galatia wọnyii pada sabẹ idè Ofin. “O dara lati mã fi itara wà fun rere nigbagbogbo.” Ṣugbọn bawo ni o ti ba ni ninu jẹ to lati ri ẹni ti o yipada kuro ninu Otitọ ti o si wá ni itara si igbekalẹ ẹtan! Ọkọ-ẹrù ni awọn Ẹlẹri Jehofa fi n kó iwe ikede ẹ̀tan wọn jade. Awọn ẹlẹkọ kò-si-Ọlọrun pẹlu imisi eṣu n kede sinu ọpọlọpọ iwe, to bẹẹ ti wọn n fẹ lati fi ewe iwe kan le olukuluku eniyan lọwọ, ọkunrin, obinrin ati ọmọde ninu ayé. Njẹ kò ha yẹ ki awa ti a jẹ́ ọmọ Ọba ni itara fun Ihinrere Jesu Kristi.

**Isaaki ati Iṣmaẹli**

Abrahamu ni ọmọkunrin meji. Isaaki lati ọdọ Sara, oun si ni ọmọ Ileri, a bi i ni ọna iyanu. Iṣmaẹli lati ọdọ Hagari, ẹrubinrin, a si bi i nipa ibi ẹda. Eyi jẹ́ apẹẹrẹ Ju nipa ti ara titi Ju nipa ti ẹmi. Awọn ti a bi nipa ti ara ti wọn si wà labẹ ide Ofin jẹ́ apẹẹrẹ awọn ọmọ Iṣmaẹli. Awọn ọmọ Abrahamu nipa ti ẹmi ni awọn ti ó wà labẹ oore-ọfẹ ti wọn si jẹ́ ọmọ Jerusalẹmu ti Ọrun, wọn kò si ninu ide. “Iwe-mimọ́ ha ti wi? Lé ẹrú-binrin na jade ati ọmọ rẹ̀: nitori ọmọ ẹrú-binrin ki yio ba ọmọ omnira-obinrin jogun pọ̀. Nitorina, ará, awa ki i ṣe ọmọ ẹrú-binrin bikoṣe ti omnira-obinrin.” Bawo ni a ba ti kun fun ọpẹ to fun ominira nipa eyi ti Kristi fi sọ wa di ominira! Ominira yii wá nipa ibi ti ẹmi lọna iyanu – ibi titun.

Ọlọrun sọ fun Abrahamu pe: “Emi o mu irú-ọmọ rẹ bisi i bi irawọ oju-ọrun, ati bi iyanrin eti okun” (Gẹnẹsisi 22:17). A ti fi awọn ọmọ Abrahamu nipa ti ẹmi wé irawọ oju-ọrun, a si ti fi awọn ọmọ Abrahamu nipa ti ara wé iyanrin eti-okun.

**Kò si Ayè Adado Laaarin**

“A ti yà nyin kuro lọdọ Kristi, ẹnyin ti nfẹ ki a da nyin lare nipa ofin; ẹ ti ṣubu kuro ninu ore-ọfẹ.” Bibeli fi ye ni gbangba pe kò ṣe e ṣe fun wa lati “la ẹsẹ mejeeji lé ọgbà.” (A ko le ṣe ọtun, ṣe osi). Bi a ba wà labẹ oore-ọfẹ, a kò si labẹ Ofin. Bi a ba fi Ofin dá wa lare, a ti ṣubu kuro ninu oore-ọfẹ. Lọjọ oni awọn ẹlomiran n gbidanwo ninu agbara wọn ati nipa iṣẹ ọwọ wọn lati lọ si Ọrun. A ni lati dá wọn lare nipa igbagbọ́ -- eyi ni pe, ki a tun wọn bi – ki wọn ba le là.

“Ẹnyin ti nsare daradara.” O ṣe ni laanu pe awọn ẹlẹkọ-eke ba ibẹrẹ rere naa jẹ́! Lọjọ oni a ni lati kiyesara ki a ma ba yapa kuro ninu Ihinrere otitọ ti a ti gbin si wa lọkan lati ọwọ awọn ti wọn ti fún irugbin ẹkọ awọn Apọsteli. Ni ọjọ Pẹntikọsti Ọlọrun fi Ẹmi Mimọ́ wọ awọn ọgọfa ti wọn fi ọkàn kan wà pọ̀. Eyi ni ibẹrẹ “akọrọ ojo.” Bẹẹ gẹgẹ ni O si tun tú Ẹmi Rẹ̀ jade sori apapọ awọn Onigbagbọ kan ni Los Angeles ni ọdun 1906, eyi ti i ṣe ibẹrẹ “arọkuro ojo.” Ọlọrun fi edidi iyọnu rẹ̀ le ẹkọ Ọrọ Ọlọrun gẹgẹ bi Ijọ Igbagbọ́ Apọsteli ti gbe e kalẹ. Lati igba naa wá ni awọn ẹlẹkọ eke ti n wá ọna lati pa awọn koko ẹkọ otitọ ti o fẹsẹmulẹ ninu Iwe Mimọ́ ti sapakan. Ọlọrun kò i ti i yipada, bẹẹ naa si ni Ijọ Igbagbọ Apọsteli kò ti i yipada ninu Igbagbọ́ ti o ti fi lẹlẹ lati ibẹrẹ.

Paulu kò ri àye fun igbọjẹgẹ. O sọ pe: “Iwukara kiun ni mu gbogbo iyẹfun wu.” “Emi iba fẹ ki awọn ti nyọ nyin lẹnu tilẹ ké ara wọn kuro.” “Ṣugbọn bi o ṣe awa ni, tabi angẹli kan lati ọrun wá, li o ba wasu ihinrere miran fun nyin ju eyiti a ti wasu fun nyin lọ, jẹ ki o di ẹni ifibu” (Galatia 1:8). Paulu waasu pe “Iwọ fẹ ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ,” ṣugbọn kò na ọwọ ibarẹ si eṣu tabi si eyikeyi ninu awọn ọmọ-

ogun rẹ̀, Ifẹ ati irẹpọ awọn Onigbagbọ́ jẹ́ iyanu; ṣugbọn ki i ṣe fun awọn wolii eke tabi fun awọn ti ó kọ̀ lati di gbogbo Ọrọ Ọlọrun mú.

**Ifẹ**

Ominira tootọ jẹ́ iyanu, ṣugbọn ki i ṣe ti anfaani lati maa rin gẹgẹ bi ifẹkufẹ ti ara tabi ti ayé. Ki i ṣe ominira nikan ni oore-ọfẹ igbala n fun ni, ṣugbọn o n fun ni ni ifẹ pẹlu. "Ifẹ ki iṣe ohun buburu si ọmọnikeji rẹ̀." "Ẹniti o ba fẹran ọmọnikeji rẹ̀, o kó ofin já. Nitori eyi, Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga, Iwọ kò gbọdọ pania, Iwọ kò gbọdọ jale, Iwọ kò gbọdọ jẹri eke, Iwọ ko gbọdọ ṣojukòkoro; bi ofin miran ba si wà, a ko o pọ ninu ọ̀rọ yi pe, Fẹran ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ"(Romu 13:8, 9).

**AWỌ\N IBEERE**

1 Ki ni ominira Onigbagbọ́?

2 Ki ni a fi wiwà labẹ Ofin ti awọn Ju wà wé?

3 Bawo ni wọn ṣe bọ́ ninu idè?

4 Ki ni tun n fa wọn pada lọ sinu idè?

5 Ki ni a fi awọn ọmọkunrin Abrahamu mejeeji wé?

6 Ọna wo ni a le fi ṣi ede yii "Ominira Onigbagbọ" tumọ?

7 Ṣe alaye bi a ṣe kó gbogbo Ofin já ninu ọrọ kan ṣoṣo.

8 Ki ni ṣẹlẹ si awọn ti o n fẹ fi Ofin dá ara wọn lare?

9 Sọ bi itara ṣe le jẹ fun rere ati fun ibi.

10 Iru iha wo ni Paulu kọ si awọn wọnni ti wọn n gbidanwo lati mú awọn ara Galatia pa Ofin mọ́?